# ÀMÌ ẸRANKO NAA
## Ifihan13:1-18; 14:9-11
## ẸKỌ 462 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Njẹ ki ẹ mã ṣọna, ki ẹ si mã gbadura nigbagbogbo, ki ẹ ba le là gbogbo nkan wọnyi ti mbọ̀ wá iṣẹ, ki ẹ si le duro niwaju Ọmọ-enia" (Luku 21:36).**

**Iyawo Kristi**

Awọn ọmọ Ọlọrun n duro de iṣẹlẹ ologo ju lọ kan. Jesu n pada bọ̀ lati mú Iyawo Rẹ̀ kuro ninu ayé yii. Ẹnikẹni ninu wa ti igbesi-ayé rẹ̀ ba ba awọn ẹkọ ti Ọlọrun fun ni ninu Ọrọ Rẹ̀ mu le jẹ apa kan Iyawo naa. Nigba ti Jesu ba tun pada wa, a o pa wa larada lọgan, ko ni si ohun ti yoo de wa mọlẹ mọ́ ninu ayé. A o goke lati lọ pade Oluwa ni awọsanma. Ki yoo si ofin ẹda ti yoo de wa. Awọn wọnni ti wọn kú gẹgẹ bi Onigbagbọ́ aṣẹgun yoo jinde pẹlu ninu ara ologo, awa pẹlu wọn yoo jumọ pade awọn eniyan mimọ́ ti igba laelae ni Ase-Alẹ Igbeyawo ti Ọdọ-Agutan.

Ṣugbọn akoko ipọnju nlá nlà yoo wà fun awọn onilọra eniyan wọnni ti ko mura silẹ lati pade Jesu. Ninu awọn ẹkọ wa ninu Iwe Ifihan, a ti kọ́ ẹkọ nipa awọn ajakalẹ arun ti yoo pa idaji gbogbo awọn eniyan ti ó wà ninu ayé. Sibẹ wahala nlá nlà ṣi wà niwaju fun awọn wọnni ti yoo kù sẹyin ninu ayé.

**Ẹranko Kin-in-ni**

Alakoso kin-in-ni ti o gba agbara ninu ẹkọ yii ni ẹni kan ti o ba ni lẹru. Lai si aniani apejuwe rẹ̀ fi agbara ati aṣẹ rẹ̀ han ju irú eniyan ti o jẹ lọ. Dragoni ti o fun un ni agbara ni Eṣu tikara rẹ̀, ti o le tan gbogbo ayé jẹ. Ẹmi Ọlọrun ko ni si ni ayé lati daabo bo awọn eniyan ati lati fi otitọ Ọrọ Ọlọrun hàn wọn. Eṣu ko ni ni nnkan kan lati ṣe idena agbara ati ẹtan rẹ̀. Yoo gba iyi nipa ipọnni. Ète rẹ̀ ni lati mu ki gbogbo eniyan sin oun.

Lati ipilẹṣẹ wa ni Eṣu ti n ba Jesu ṣe ọta. O ti gbiyanju lati jin agbara ati aṣẹ Rẹ̀ lẹsẹ. Nigba ti a bí Jesu sinu ayé lati jẹ́ Olugbala araye, Eṣu kó si ọkàn Hẹrọdu lati pa gbogbo awọn ọmọ kekeke, ni ireti pe dajudaju, Jesu yoo wà ninu awọn ti a pa. Ṣugbọn Ọlọrun ti kilọ fun Josẹfu lati gbé Jesu lọ si Egipti ki nnkan yii to ṣẹlẹ, nipa bayi a dá ẹmi Jesu sí. Nigba ti Jesu fẹrẹ bẹrẹ iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀, Eṣu gbé E lọ si ori oke giga, o si gbiyanju nipa idanwo pupọ lati mu Un tẹriba fun oun – o gbiyanju lati fi hàn pe Eṣu ni agbara ju Jesu lọ. Ṣugbọn ni gbogbo igba ati akoko ni Jesu ṣẹgun Eṣu. Jesu lagbara ju Eṣu lọ -- nigba gbogbo ni O ni agbára, paapaa nigba ti O wà ni aye gẹgẹ bi eniyan. Jesu wi pe: "Gbogbo agbara li ọrun ati li aiye li a fifun mi" (Matteu 28:18). O fi eyi hàn pẹlu, nigba ti O jinde kuro ninu oku. Eṣu rò pe oun ti ṣẹgun nigba ti a kan Jesu mọ́ agbelebu. Nisisiyii Jesu ti kú Eṣu yoo si ṣe akoso ayé. Ṣugbọn Jesu jinde ni ọjọ kẹta, O ni iṣẹgun lori iku, isa-oku ati ọrun-apaadi. Nigba ti Johannu kọkọ ri Kristi ti a ṣe logo ni Erekuṣù Patmo, Jesu wi fun un pe: "Emi li ẹniti mbẹ lãye, ti o si ti kú; si kiyesi i, emi si mbẹ lãye si i titi lai, Amin; mo si ni kọkọrọ ikú ati ti ipo-okú" (Ifihan 1:18).

**Ọgbẹ Aṣapa San**

Ninu iran yii ti Johannu ri nipa awọn ohun ti n bọ̀ wá, Eṣu n fẹ ṣe ohun ti Jesu ṣe. Ori ẹranko yii ni "a ṣá pa, a si ti wo ọgbẹ aṣapa rẹ̀ na san" (Ifihan 13:3). O n gbiyanju lati fi hàn pe, oun lagbara gẹgẹ bi Jesu, lati fi ẹmi oun lelẹ ati lati tun gba a. A si tan awọn eniyan ayé jẹ nipasẹ rẹ̀. A sọ bayii pe gbogbo ayé si fi iyanu wo ẹranko naa. Wọn yin in logo, wọn si sin in. Wọn beere wi pe, "Tali o dabi ẹranko yi? tali o si le ba a jagun?" Nigba yii ẹranko naa ro pe oun jẹ́ ẹni kan pataki. Ọwọ rẹ̀ ti tẹ ohun ti o n fẹ́. O n ṣe akoso ayé. Gbogbo eniyan ni wọn n foribalẹ fun un. O sọrọ odi si Ọlọrun. O sọrọ odi si Tẹmpili Ọlọrun, o si sọ ọrọ odi si awọn eniyan Ọlọrun paapaa ti wọn ti bọ́ kuro lọwọ rẹ̀, ti a ti gbala, ti wọn si ti lọ si Ọrun.

Eyi ma buru pupọ o, ṣugbọn ẹranko miiran yoo jade wá ti yoo ran ẹranko kin-in-ni lọwọ. Yoo fi ipá mu awọn eniyan lati sin ẹranko kin-in-ni, gẹgẹ bi wọn ṣe ni lati sin Ọlọrun. Awọn miiran lonii ti bẹrẹ si sin eṣu, ṣugbọn ni ọjọ naa olukuluku eniyan ni a o fi agbara mú lati sin awọn ẹni buburu wọnyii. Ọpọlọpọ eniyan ni wọn ni ifẹ lati ri iṣẹ ami -- awọn ohun ti o ṣẹlẹ ti o ju ti ẹda lọ -- ju ifẹ ti wọn ni si gbigbe igbesi-ayé iwa mimọ́ lọ. Kò ni ṣoro lati tan iru awọn eniyan bayii jẹ. Wọn yoo ri iṣẹ ami pupọ nigba ti awọn ẹranko wọnyii ba n ṣe akoso ayé. Awọn ẹranko wọnyii yoo lagbara lati pe ina sọkalẹ lati ọrun wá. Wọn yoo ni agbara paapaa lati mu ki ère sọrọ. Ẹnikẹni ti o ba si kọ̀ lati sin awọn ẹranko wọnyii ni a o pa.

**Agbara Iṣelu**

Ọlọrun yoo fi àye silẹ fun awọn ẹranko naa lati ṣe akoso fun oṣu mejilelogoji lẹyin igba ti o ba ti da majẹmu ti o ba awọn Ju dá: ki i ṣe nitori ọran ẹsin nikan – ti yoo si buru pupọ si -- ṣugbọn yoo ṣe akoso pẹlu ọgbọn oṣelu ati ọgbọn òwò ṣiṣe. Ki yoo si ọba tabi alakoso kan ti yoo ni agbara ju u lọ. Yoo fi agbara mu awọn

eniyan lati gba ami rẹ̀ si ara wọn – yala si ọwọ wọn tabi si iwaju wọn. Ko si ẹni ti yoo le tà tabi ti yoo le rà lai si ami naa. Eyi kan olowo ati talaka (ko ni si ẹni ti yoo fi owo ra oju rere rẹ̀), awọn ẹni ti o n gbà ni si iṣẹ́ ati awọn ti a n gbà si iṣẹ, eniyan lati orilẹ-ede gbogbo, ọkunrin, obinrin ati awọn ọmọde. Boya wọn ko ni le ṣiṣẹ lati ni owo; awọn ti wọn ni owo paapaa ko ni le fi owo naa ra ounjẹ tabi aṣọ. Ẹranko naa yoo ni agbara patapata.

**Awọn Eniyan ti a Kà**

Akoko wà nigba ti o dabi ẹni pe ko ni ṣe e ṣe lati wá olukuluku ri ki a si ni akọsilẹ nipa rẹ̀. Ṣugbọn lonii, olukuluku eniyan ti o wà ni ilu Amẹrika ati awọn ilu miiran gbọdọ kọ́ fi orukọ silẹ, ki o si gba iwe ọwọ́ ki o to le ri iṣẹ ṣe. Awọn ẹrọ igbalode ti o n ṣiro nnkan le kọ gbogbo iye awọn eniyan ki o si ṣe akọsilẹ olukuluku wọn. Awọn ilu miiran le ṣe iru eto yii pẹlu iṣoro diẹ. Nigba ti Aṣodisi-kristi (ọkan ninu awọn ẹranko wọnni) ba gba ijọba, ki yoo ṣoro fun un lati fi apejuwe kun iwe ọwọ́ olukuluku eniyan – nigba naa ni yoo ni awọn otitọ ti o fẹ mọ nipa ẹni kọọkan. Yoo mọ̀ boya awọn miiran n fẹ sin Jesu, yoo si jẹ ki a pa oluwarẹ̀ lẹsẹkẹsẹ. Yoo fi dandan le igbọran patapata lati ọdọ olukuluku eniyan.

**Ibinu Ọlọrun**

Awọn eniyan pupọ ni yoo gbiyanju lati gba ara wọn silẹ ninu ipọnju, nitori naa wọn yoo ṣe ohun ti Aṣodisi-kristi n fẹ ki wọn ṣe. Eyi yoo mu ibinu Ọlọrun sọkalẹ. Ọlọrun yoo maa ṣe akiyesi ohun gbogbo ti o n lọ ninu ayé, ati nigba ti oṣu mejilelogoji naa ba pari, yoo rán idajọ ti o tobi ju lọ ti eniyan ko i ti mọ̀ ri sori ayé. Ibinu Rẹ̀ yoo jẹ "ni aini abula" – ko ni si aanu rara. Lọjọ oni, Ọlọrun maa n jẹ ẹlẹṣẹ niya nigbakuugba fun iwa buburu rẹ̀, ṣugbọn sibẹ O n fi aanu hàn pẹlu. Bi ẹlẹṣẹ naa bá ronupiwada, Ọlọrun yoo dá iya naa duro, yoo si dariji i. A kà nipa awọn apẹẹrẹ miiran ninu Bibeli nibi ti awọn ẹlẹṣẹ ti wọn buru pupọ rẹ ara won silẹ diẹ, ti Ọlọrun si sún idajọ siwaju. Lootọ nigba ti ẹlẹṣẹ ba ronupiwada ti Ọlọrun si dariji i, ko ni si idajọ mọ́ rara. Ṣugbọn nigba ti Ọlọrun ba mu idajọ wa ni akoko Ipọnju Nla, kò ni si aanu.

Olukuluku ẹni ti o ba ti gba ami ẹranko naa ni a o maa dá loro lae ati laelae ninu adagun iná. Wọn ki yoo ni isinmi lọsan tabi loru lati akoko naa lọ titi lae. Ko ni si opin fun idajọ ayeraye Ọlọrun. Jesu, Ẹni ti O ti fi aanu lọ̀ wọn lẹẹkan ri, ti O ti pè wi pe, "Ẹ wá sọdọ mi, gbogbo ẹnyin ti nṣíṣẹ, ti a si di ẹrù wuwo le lori, emi o si fi isimi fun nyin," yoo ri ohun ti o ṣẹlẹ si wọn. Yoo ri awọn ti wọn tutọ si I lara ti wọn si kan An mọ agbelebu, ti wọn wi pe, "Ki ẹ̀jẹ rẹ̀ wà li ori wa, ati li ori awọn ọmọ wa" (Matteu 27:25) ninu oró.

**Egbe Ayeraye**

Ha, i ba ṣe pe awọn ọdọ le mọ jamba ti o wà ni kikọ̀ lati sin Ọlọrun lonii! Awọn miiran n gbiyanju lati ro ọna ti wọn yoo fi le yọ nigba Ipọnju Nla. Ṣugbọn bawo ni wọn ṣe mọ̀ pe awọn yoo wà laaye titi di akoko naa? Ẹnikẹni ti o ba kú lai ronupiwada awọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀ yoo ṣegbe titi laelae. Ko ni si àye miiran lati bọ́ kuro ninu ibinu Ọlọrun. Titi lae ninu ọrun-apaadi! Ẹkún ati ipahinkeke yoo wà. Eefin oró wọn yoo goke titi lae! Kò si opin! Wọn yoo sọnu titi lae!

**Ifẹ Ọlọrun**

Lọjọ oni, Oluwa n na ọwọ ifẹ Rẹ̀ jade. O n pe gbogbo eniyan lati pada wá si Ile, si Ile Baba. Ronu le awọn ọrọ daradara ti n tu ni ninu wọnyii: Ile, Baba, awọn ọrẹ, ifẹ, ounjẹ, itunu, isinmi, alaafia, ati ayọ̀. Jesu ti lọ pese àye silẹ fun wa, O si fẹ tun pada wá lati mu wa lọ si ile pẹlu Rẹ̀ nibi ti a o jẹ́ alabukun fun titi lae. Ki ni ṣe ti o kò ni sin In? O wi pe bi nnkan kan ba tun wà ti Oun le ṣe fun igbala wa, Oun i ba ti ṣe e. O ti san asanpari owo irapada wa lori Kalfari lati gbà wá là kuro ninu awọn ẹ̀ṣẹ wa. Bi awọn eniyan ba kọ igbala Rẹ̀, wọn ni ẹtọ lati jiya ninu ọrun-apaadi titi lae.

Ko si ọna abayọ kuro ninu yiyan Ọrun alaafia tabi ọrun-apaadi. Olukuluku ẹni ti a ti bi si ayé yoo lọ si Ọrun Rere tabi si ọrun apaadi. Ẹni kọọkan ninu wa ni o ni agbara lati yàn. Ẹ jẹ ki a pinnu pe ohunkohun ti o le de, a o gbọran si Ọrọ Ọlọrun a o si fi Ọrun Rere ṣe Ile wa titi lae.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni gbogbo awọn Onigbagbọ́ tootọ n fojusọna si?
2 Ki ni yoo ṣẹlẹ ninu ayé lẹyin ti a ba ti gba Ijọ Akọbi soke?
3 Ki ni Eṣu ti gbiyanju lati ṣe fun Jesu?
4 Nibo ni ẹranko naa yoo ti gba agbára rẹ̀?
5 Bawo ni ẹranko naa yoo ti ṣe afarawe ikú ati ajinde Kristi?
6 Sọ diẹ ninu awọn ohun ti ẹranko naa yoo ni agbara lati ṣe.

7 Ki ni yoo ṣẹlẹ si awọn eniyan wọnni ti wọn yoo kọ̀ lati sin ẹranko naa?
8 Ki ni awọn eniyan yoo ní ki wọn to le rà tabi ki wọn to le ta nnkan?
9 Ki ni Ọlọrun yoo ṣe fun awọn eniyan wọnni ti wọn ba gba ami ẹranko naa?
10 Bawo ni a ṣe le sá asala fun Ipọnju Nla naa?